26 MAR 1974
EDITOR IMOLE OWURO
23/3/74

JOVIAL NAPS
NAP 7, 11, 24
Perm 7, 8, 9, 10, 27
Pairs (48&45) (20x 18) (14&16)
If no 7 draws, come for 3 Sure draws in wk 35
M. O. Oketona
Apomu - Ikire
(7xxbk?)

Imọlẹ Owurọ

Esin oro wa "IMOLE DE OKUNKUN PARADA"

UNITY NAPS
For 3 sure draws in Wk 34 try to see The Manager Unity Pools House E4/226, Gbelekale Ibadan
See him with N5 before 2 p. m. on Saturday
5 20 26 45

Independent Paper VOL. XI No 632 SATURDAY MARCH 23 — FRIDAY MARCH 29, 1974 4K. (KOBO MERIN)

# 'ABURO LO RAN WA LATI PA EGBON RẸ SILE'

## — Alagbapa

ILE Ejọ giga kan nilu Enugu ni Ipinlẹ Aarin-gungun Ila-Oorun gbọ itan bi awọn ṣe sọ pe aburo ọkunrin Dokita onimọ ijinlẹ kan gba awọn alagbapa kan pe ki nwọn ba oun yinbọn pa ẹgbọn rẹ ti iṣe Dokita na.

Ninu ẹjọ ẹsun apania ti nwọn mba awọn ọkunrin marun ṣe pe nwọn pa ọkunrin Dokita kan ni ọrọ na ti jẹjade. Awọn afẹ—sunkanni ni o fi ẹsun kan awọn eni na pe nwọn gbimọpọ pa Dokita George Obinwa ti iṣe onimọ ijinlẹ pataki kan ni ile iwosan Yunifasiti Nsukka ni ọjọ kejidinlogbọn oṣu karun ọdun ti o koja.

Awọn ọdaran na ni: Patrick Ubaka Obinwa ti iṣe aburo Dokita na, Paulinus Udebibia ti inagijẹ rẹ njẹ "Appo—llo", Sylvanus Obiekwe ti inagijẹ rẹ njẹ "Bob cash", Ohanuka ti inagijẹ rẹ njẹ "Organiser", ati Johnson Ajuluchukwu.

Nigbati awọn ngbọ ẹjọ na lọ, ile ẹjọ gbọ bi afẹsunkanni ṣe nka ẹjọ ti ọkan ninu awọn ọdaran na ro sinu iwe ni ago Ọlọpa jade. Ọdaran na ni Johnson Ajuluchukwu.

Ninu ẹjọ na ti awọn afẹsunkanni sọ pe ọdaran na finnufindọ kọ silẹ ni kete bi ọwọ Ọlọpa ti tẹ ẹ tan, o sọ pe:

"Aburo Dokita na, Patrick Ubaka Obinwa l'o bẹ wa ni iṣẹ ala—gbapa pe ki a ba oun fi ibọn pa ẹgbọn rẹ kan ti njẹ Dokita George Obiesie Obinwa, ẹgbẹẹdogun Naira (N3,000) ni o si fun wa gẹgẹbi owo iṣẹ na"

Siwaju si i, ọdaran na sọ pe: Ni ọjọ kejidinlogbọn oṣu karun ọdun 1973, oun ati awọn ẹlẹgbẹ mi mẹrin yoku pẹlu awọn meji miran ti nwọn ti na papa bora, bọsicu mọto ayọkẹlẹ Pijo kan LS 4523 lati ilu Nnewi. A ti Onitṣa bọ si Enugu nibiti ẹniti o bẹ wa niṣẹ alagbapa sọ pe ẹgbọn rẹ Do—kita na ngbe.

Nigbati o ku iwọn buṣọ mẹsan ki a wọ ilu Enugu nibi kọrọ kan bayi, a duro, nibẹ si ni ẹniti o bẹ wa n'iṣẹ na ti gbe paali ọti kan ti a mu fun wa; a si jẹun pẹlu ni ile itura kan ti ko jin-na sibẹ nitori gbogbo wa ni a gba lati jẹun nitoripe "Ẹda yio sa jẹun".

Lẹhin onjẹ na ni a mba ajo wa lọ, a si ri i pe agogo meji ọganjọ oru lu ki a too de ile ti Dokita na ngbe ni adugbo ti njẹ River Lane;

Iṣẹ ti ẹgbẹ wa fun ẹnikọọkan ṣe ni pe, emi Johnson Ajuluch-ukwu ni mo nilati joko pa sidi kata ọkọ pẹlu ẹṣẹ pe mo gbọdọ gbaradi lati f'ina si ọkọ l'ojiji bi ọrọ ba ba bẹẹ wa.

Paulinus Udebibia ni yio yinbọn lu Dokita na; Sylvanus Obiekwe ni yio fọ ilẹkun iyara

(Woju ewe kẹjọ)



Awọn Iya w..uy. iati ilẹ Germany nkọ [illegible] wọn l'are Idaraya.



# ATIORO OMO ATIALA

## EWE IWOYI [4]

Nigbati a ba nsoro ilodisi
L'ori iwa ewe iwoyi,
A maa jo bi eni pe
A ki i rire wi
Nipa ohun
T'awon ewe nse ni,
Awon miran npe wa
Ni ope enia
Ti ko mo pe
A gbodo maa b'aiye yi ;
Nwon a ni
B'o ba se pe a mbaiye
yi
A ba mo ohun ribiribi
T'awon ewe nse
Ninu igbesi aiye
Iran omo enia.
Awon miran ewe
Si le pe wa ni
Eniti ngbejo apakan da,



Nwon a ni
K'a too da ewe lejo
O ye k'a gbo t'enu won,
Nwon a ni
Bawo l'a se le soro
K'a ma ri agba bu.
A fi ki a maa bu
Awon ewe nikan
K'a si waa so
Awon agba di maleeka!
Bi a ba r'iru enia
Ti nso bawonyi,
O daoi eni pe
Nwon ko ro o gun
Ki nwon too soro won.
Nitoripe bi a ko ba
gbimopo
K'a diju ba ole wi,
Lai sawawi
Ojo t'ole ba d'orisa tan
Apa olohun ko ni i le
ka a,
Igbehin gbehin
Ole yio d'oran
Si gbogbo ilu l'orun
Ani b'omode
Ba nhuwa aito
T'a nf'adi pa a l'ori,
Ti a wi f'omode
T'omode ngboni l'oju
T'omode nta ni l'enu
T'omode bugada

T'o ni omugo l'agba;
Sugbon t'omode
Nse nkan wonyi
Ti a ni, ko se nkan;
Ti a r'otito oro
Ti a ko, ti a ko so;
Ti a nso pe
Ni ilu Gba-edu,
Ni ile Safara,
Bee l'awon ewe nse
Nitori akoko majesin
l'o de
Igba awon agba ti lo!
Ko buru,
Ko baje
A o maa wo nyin n'iran
A o maa wo ona
Ti e o ba lyara ja
Nitorina, gbogbo enia
T'o ba lodi si pe
K'a b'awon odo wi,
Gbogbo eni pata
T'o ba ndunnu si
Bi nwon se nse,
E ba ronuwo
Ki e piwada;
E je k'a gbimopo
K'a jo ko 'hun ti ko
dara
T'awon ewe wa nse
K'o ma waa deh'n eran
K'a ma fika abamo bo-
nu.
E ranti omode ijosi
Ti nwon se ipade
Pe, kawon pa gbobbo
agba
K'awon le ribi pase ilu;
E si wo omode kan
T'o gbe baba re pamo
Pe, oun ki yio pa t'oun;
E si ranti
Igba ti nwon pa agba
tan
T'ilu daru mo won lowo
Ki o too di pe
Baba t'omo re gbe pamo
L'o ko won yo
Ninu iparun!
Lehin oro yi
L'awon ewe yi kabamo,
Nwon ni ko dara
Bagba ba tan
L'ori ile aiye;
Nwon ni
Nitori ojo agba ba tan
Ni ilu baje pata;
Nwon n'ijo Baale ku
Dandan ni kile dahoro
Abajo! awon
Baba wa so pe :
Bomode mo asare ko
Ko le mo atetetebe!
Nwon ni
B'o ti wu kedo mo ori
ije to,
Yio yi i lowo
Yio yi i lenu,
Ani bo ti wu
K'edo iwoyi mowe to
Bi nwon lajulaju
T'o ju t'Ojukwu lo
O ye ki nwon mo pe.
Omode gbon,
Agba na gbon,

L'a fi dale Ife,
Oto logbon iwe,
Oto l'ogbon adaiyeba;
K'a fowosowo
L'o le mu
Kaiye dara fun gbogbo
wa
Ki ise kodo waiyami
K'o so p'enu agba arun
K'o maa so pe
Odo lo le sohun gbogbo.
Nje b'omode ba raja
T'o so o ni
"Ki t'agba ma se",
Ikooko ki yio ha paja ae
je
Nitorina enyin enia
Ti ngbo nasia yi,
A ko ba odo wi rekoja
Sugbon a nkesi won
Lati mase tapa sofin
Ati lati ma so pe
Enu agba nrun;
Ati lati mase so pe
Awon nikan l'awon gbon
Nitori "Ofua wo o,
Iwori wo o,
Ohun a ba dijo wo,
Gege ni i gun"

OLOLA ATIORO

# Oyelade di Aragbiji Iragbiji

EGBERUN enia ni o woran ayeye fifi ewe oye le Omo Oba Timothy Adepeju Oyelade lori gegebi Aragbiji Iragbiji. Oba Oyelade, eniti ise oga Lagbowaka nile isowo John Holt nilu Ibadan gori ite na ni ojo Eti ti ise ojo kedogun osu yi.

Oba titun yi ni o ropo Oba Joseph Oyedokun ti o waja ninu osu keji'a odun 1967.

Ninu oro re nibi ayeye na, Oba Adepeju Oyelade dupe gidi gidi lowo awon enia re fun ife ati ifowosowopo won, eyi ti o se pe o mu ki gigori ite oun rorun.

Bakanna ni Oba titun na dupe lowo Gomina Ogagun Oluwole Rotimi ati Ijoba Ipinle Iwo-Oorun fun fifowesi iwe ti nwon fi [illegible]yan oun si aye na.

Nigbana ni Oba titun na se ileri lati lo ipo oun na ni rere fun ilosiwaju ati irepo awon enia ati ilu oun. Oba waa ro awon enia na lati maa pa ofin mo, ki nwon si maa sanwo ori won daadaa.

Opo awon enia nlanla l'o wa sibi ayeye na.



OLOYE AKINYEMI
Ajele Oran Lobaloba

## 13 23 34 42



Aworan egbe yi nse afihan apa kan ninu ere (Film) kan ti nje "IFE AKOKO" ti nwon nduwo kaakiri ile Russia nitoridi— dua ti o dun. Nwon se ere na ni ibamu pelu itan kan ti awon pe ni ti Turge— neu.

# Nibo L'esin Igbagbo nlo ? (3)

"ẸNITI mo ti mu lati opin aiye wa, ti mo ti pe ọ lati ọdọ awọn Olori enia ibẹ. Ti mo si wi fun ọ pe. Iwọ ni Iranṣẹ mi; mo ti yan ọ. Emi ko si ni i ta ọ nu; Iwọ ma bẹru, Nitori mo wa pẹlu rẹ; ma foiya, nitori emi ni Ọlọrun rẹ: Emi o fun ọ ni okun; nitootọ Emi o ran ọ lọwọ nitootọ Emi o fi ọwọ; ọtun ododo mi gbe ọ soke. Kiyesi i, gbogbo awọn ti o binu si ọ ni oju o ti, nwọn o si daamu: nwon dabi asan; awon ti o si mba o ja yio ṣegbe" Isaiah 41, 9—11:

Eyi ni yio ṣe igba kẹta ti a ti nsoro l'ori akole iwaasu yi pe "Nibo ni esin Igbagbo nlo?" ninu eyiti a fi nso opo Iwa buburu ti awon ti nṣakoso Ijo Olorun l'oni fi mba Ijo Olorun jẹ, eyi na ewẹ l'o si mu wa ketentan pe "Nibo ni esin Igbagbo nlo?"

Njẹ nitorina enyin Ojiṣẹ Ọlọrun gbogbo ti Oluwa ti yan sinu Ijo kọọkan ninu aiye, ẹ ranti pe Oluwa feran nyin pupopupo, nitorina ni Oluwa si ṣe yan nyin si Iṣẹ Iranṣẹ eyiti o yẹ ki enyin je rere gegebi ifẹ Ọlọrun, ki e si maa fi ayọ reti ere re ti Baba ti pese sile fun nyin.

Ere ti ẹ o jẹ na ni ileri ti Oluwa ṣe fun nyin ninu ẹsẹ wura ti a tọkasi l'oke nni. Ẹ ranti pe, ileri Oluwa yi ju agbara eṣu lọ ninu aiye: Ani bi o ti wu ki owo tabi dukia rẹpẹtẹ ti ọdọ eṣu wa to, ko tọ, ko si yẹ fun Ojiṣẹ Ọlọrun lati wobe mọ, bikoṣe ki o maa mu asotele Oluwa ṣe si Ijọ enia Ọlọrun lara ninu aiye, ti Oluwa sọ pe: "Njẹ nigbati ọmọ enia ba de, yio ha ri igbagbọ li aiye ?—"Luku 18, 8.

Njẹ bi Jesu Kristi ba de ti ko ba Igbagbọ li aiye, kini yio ha jẹ iṣẹ igbagbọ awọn ti Oluwa yan sori

LATI ỌWỌ WOLI S. I. OWOẸYẸ

wo ibukun lati ọdọ Oluwa eyiti o nmu ni la lai fi laalaa kun un.

Nitorina, mo rọ gbogbo awọn alaṣẹ ninu gbogbo Ijọ Jesu Kristi l'aiye lati maa ṣe atunṣe tootọ fun awọn Ojiṣẹ Ọlọrun ti o wa labe nyin, paapaa julo nipa iranlowo nipa omo won ati lati maa fun won ni owo oṣu ti o to fun Iṣe won:

Nigbati a ba ti ṣe nkan wonyi tan eni yowu ninu Ojiṣẹ Ọlọrun ti o ba huwa aleebu lenu iṣẹ rẹ yio gba idalẹbi lọkan ara rẹ.

Nkan wọnyi ni o nfa iṣubu ọpọ Ojiṣẹ Ọlọrun l'ode oni, ati iya laarin Ijọ ati iwa ibajẹ gbogbo miran, eyiti o le Ijọ kọọkan ati oṣiṣẹ ile isin gbogbo pẹlu awọn ti nwọn nlo Bibeli Mimọ kiri fun ipadabọ Jesu Kristi ?

Njẹ bi iwọ ba nrọ pe iwọ nikan kọ ni yio jiya ẹṣẹ yi, ranti pe awọn ti nwọn mọ ifẹ Oluwa, ṣugbọn ti nwon ko ṣe e ni yio jiya julọ.

Njẹ, tani awọn wọnyi ? Ani omọ ọdọ na ti o mọ ifẹ Oluwa rẹ ti ko si mura silẹ ti ko si ṣe gege bi ifẹ Rẹ, oun li a o na pupọ, ṣugbọn eyiti ko mọ, ti o ṣe ohun ti o yẹ si lilu oun ni a o lu niwọn; nitori ẹnikẹni ti a fun ni pupọ, lọdọ rẹ li a o gbe beere si i" Luku 12, 47-48.

Njẹ o ha yẹ ki iya tun maa jẹ Onigbagbọ ju alaigbagbọ lọ? Ẹ ranti pe ki iya wonyi ma baa jẹ wa ni Oluwa ṣe ileri fun gbogbo Ojiṣẹ Rẹ t'o yan sinu aiye, eyiti o fi jẹ pe egun gidigidi ni fun ẹnikẹni ti o ba tapa si eniti Oluwa yan lotito ati lododo.

Eṣu paapaa mo pe awon ogun orun ala t'o lagbara lo mba awon Ojiṣe Ọlorun gbogbo ṣiṣe po, eyiti o le pa Ijoba eṣu run.

Nitorina ni eṣu ṣe da ọgbọn ti o fi ṣi ile itaja re siwaju ogunlọgọ Ijọ loni. Njẹ ẹ tilẹ mọ awọn nkan ti eṣu nta ninu ile itaja rẹ na? Awon oja eṣu na ni: nini ifẹ owo ju Ọlorun lọ, fferan agbere ju ohun gbogbo lọ. Amupara ati tẹtẹ tita, igberaga, imọtaraẹni nikan, kataba mimu, ojukokoro, ole, ati bẹẹbẹẹ lọ. Njẹ o ha ye ki iwọ eni iwabi-Ọlọrun tun ba wọn ra ninu ọja wọnyi? Torina tewọ adura.



WOLI S. I. OWOẸY[...]

Oniwaasu na

ADURA

Oluwa, ọrọ Rẹ ni gbọ yi ; jọwọ Ol[...] nitoriti eṣu ti pa[...] niwaju Ọmọ Re [...] Kristi; ti eṣu [...] pada kuro l'ọdọ [...] torina Oluwa, ma [...] ko atẹ eṣu kuro n[...] ju mi ati niwaju [...] Re gbogbo ninu [...] Oluwa, jọwo fi mi [...] ipo rere ki o le [...] mi ni imurasilẹ [...] iṣe rere nigbagbe[...] ti ng o fi jẹ ipe [...] nigbehin aiye mi. A[...]

## ANFANI FUN O

Kinni iṣoro rẹ? Kinni ẹdun ọkan [...]
Kinni o nru ọ loju? iwọ ha nlalakala b[...]
Tabi ohunkohun nru ọ loju ninu Bibeli [...]

Ọfẹ ni a o fi gbogbo nkan wọnyi ye [...]
Fi apo iwe ti o lẹ Stamp 5k mọ ara [...]
pẹlu address rẹ sinu iwe ti o ba kọ si m[...]

Ero mi ni lati fi ẹbun ti a fun mi r[...]
araiye lọwọ.

Kọwe si:-
Woli S. I. Owoẹyẹ
N6/765A Kabiawu Street,
Mọkọla Ibadan.

ASỌTẸLẸ

"Ibi ni yio pa enia buburu ati awọn ti korira olododo yio jẹbi" Orin Dafidi 34, [...]

# Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Owurọ

10,619 Jimọ Ọladunni Eko

10,620 Rasaki Buraimọ, Kaduna

10,621 Alideen Ọlatoye, Ikire

10,622 Oluyẹmi Amoon, Ijẹbu

10,623 Comfort Akande, Ogbomọsọ

10,624 Raimi Owolabi Eko

10,625 Siamlatu Ọlatunji, Ọyọ

10,626 Bilikisu Awẹni, Ogbomoṣọ

10,627 Moses Oyerinde, Ogbomọṣọ

10,628 Taiyewo Ariyibi, Ibadan

FUN IGBEGA EDE ATI AṢA YORUBA DI

**Omo Egbe Imole Owuro**
(Iwe Idi omo Ẹgbẹ)

Oruko rẹ ______________________

Adirẹsi rẹ: ______________________

Ọmo Ilu ti o jẹ: ______________________

Jawe yi ki o si poosu rẹ si
DOKUN AJADI
(Akowe Ẹgbe)
P. M. B. 5230, Ibadan



# AGEKURU ITAN ILU Ogbomoso

(34)



QBA QLATUNJI ELEPO KEJI
Şehun Ijerin ni Ogbomoşo

AKIYESI

Ki a to pari itan Ikoyi mo fe ki awon ologbon se akiyesi ohun pataki kan ninu itan ti a ti mba bo; Eyi ni sisi ife laarin awon Yoruba ti nwon fi gbe ilu won ta fun orile-ede miran, Oro naa wa dabi owe Yoruba kan ti o wipe "Ega kole, ega fi esu tu u" Beeni oro naa ri nigbati a wo gbogbo itan naa finifini, A o ri re, biotilejo pe awon oba siade po ninu ijoba nla naa, sibe nwon mbu ola fun Oranmiyan gege bi eniti o repo baba won. Ijoba naa wa ti ti o fi de aiye Alaafin Onigbogi ti o fi aseju ba a je ti awon Yoruba fi kehin si i; nwon pe Tapa wa, Tapa le e lo si ile Ibariba gege bi a ti wi saaju.

Qba Moro pada wa si Oyo, nwon tun Ijoba

LATI QWQ OLOYE S. O. BADA

I pe oro naa ba Oyo wi pupo.

Itan so fun wa pe, Oduduwa ni o fi ipile Ijoba ria Yoruba lele ti o bere lati Odo Oya de Okun Benin ati Popo, Nigbati ko si Oduduwa, Oranmiyan ti se abikehin ninu isori keje repo re ni Ilefe, o si jogun Ijoba nla naa. Lehin eyi, o wa i Oyo se ibujoko ijoba naa se şugbon ko dabi ti akoko mo. Nigbati o di akoko Alaafin Aole nigbati o wa ni omode, oun ni o se Afonja ti Afonja fi da setria fun un, şugbon emi igbesan mu ki o fe gbesan lara Afonja ti gbogbo nkan fi daru. Beeni o tun ri nigbati o kan Oluewu ati Atiba omo oba.

Lehin rudurudu bayi, nkan tubo mburu si I ni: Awon alagbara Eku-Osi, Solagberu ati Adegun Onikoyi ko re, Adegun, Edun Aare—Onakakanfo ati Toyeje Aare—Onn Kakanfo, keji ko re, Adegun Onikoyi ni o fi Edun je Kakanfo, oun naa ni o si pa a ni ogun Kanla. Bayi ni awon Yoruba fi aiferan ara won ba ilu ara won je

Lehin ti Ijoba nla ile Yoruba baje, ti gbogbo Eku-osi ati opolopo ile Yoruba kuro labe isin Alaafin, ti o wa ku ile die ni owo Alaafin; a fi Atiba je Oba ni Ago Oja, Oluyole ni Ibadan, Kurunmi ni Ijaye; ni Eku-otun Okere Saki fun Maje-obaje (Baba-isale) ati beebee lo. Ko pe lehin ti a se awon nato won-yi tan ni adeaiyede kan be sile laarin Alaafin Atiba ati Basorun Oluyole

Kurunmi duro ti Alaafin pe, Oluyole ko gbodo yaju si Alafin ni oju oun. Eyi ni o di Ija laarin Oluyole ati Kurunmi Ijaye. Eyi naa ni o si tu Ile Ijaye. Lehin eyi ni ija tun bere laarin Alaafin Adeyemi Kini ati Aare Latoosa ki ogun Ekiti Parapo too bere, Bi ko ba si si Oyinbo Gessi ti o pari Ija naa lehin odun merindinlogun ti ija naa ti bere, Olorun ni o mo ohun ti o le gbehin ile Yoruba ni ojo wonni!

A ko ise awon Oba ati awon enia nla sile ninu Bibeli lati maa ko eko nibe: Beeni o ri ninu itan awon Oba ile wa ati awon enia nla ibe lati ko eko ninu iwa won.

Eniti o ba ni eti lati fi gbo, je ki o gbo.

29
33



## Ile—Iwe eko larubawa bere

Ile Iwe eko ofe Larubawa yio bere ni ile iwe Larubawa giga kan (Islamic Institute of Nigeria) ni adugbo Elekuro nilu Ibadan laipe yi.

Iru eto eko ofe Larubawa yi ni yio je akoko iru re ni ile Naijiria ti o si waiye lati odo Ijo Musulumi kan nilu Ibadan eyiti Alhaji Muritala Salami ise Olori re.

Bakanna ni awon Ijo na nseto lati tan anfani eko Larubawa na kakiri Orile—ede yi paapaa jakejado Ipinle Iwo—Oorun.

Ninu ipade kan ti awon Ijo na se pelu awon oniroin, nwon so pe eto eko ofe yi je eyiti awon ti nse akitiyan re ki anfani ba le wa fun awon akeko ti awon obi won ko lagbara to lati maa sanwo ile eko won.

Olori Ijo na Alhaji Muritala Salami wa salaye pe pelu ogo Olo—run ile Iwe oun ti ri iranlowo ti o le ni Millonu meta Naira gba lati owo Ijoba ile Saudi Arabia, eyiti awon yio maa na lati fi ba eto eko ofe na lo.

Ninu ibere kan lati enu awon oniroin, Alhaji Muritala dahun pe opolopo awon akeko ti o njade ni ile iwe oun ni nwon tun ti tesiwaju si I ti nwon si wa ni ile eko giga Yunifasiti l'ori eko ede Larubawa.

O waa menuba nkan ti Ijo oun fe dawole nisisiyi ninu eyiti ise kiko Mosalasi si ile iwe na ati eyi ti awon akeko yio maa gbe.

Alhaji Muritala dupe lowo Ijoba ile Saudi Arabia ati Alakoso eto ofin ni Ipinle Iwo-Orun Naijiria Ojogbon Latee—ef Adegbite fun iran—lowo won gbogbo lati si I pe eko Larubawa ndagba s'oke si i, ati pe esin Islam ko rehin rara.

# 'Agbe yinbon pa Agbe' —AFESUNKANNI

Awọn Ọlọpa ilu Agbọ ni Ipinlẹ Ado—Ibonni ti fa ọkunrin agbẹ eni ọdun mẹẹdọgbọn kan Issac Enyecsa ara abule Ekuku-Agbọ ni agbegbe Ika wa sile ẹjọ Senior Magistrate kan ni ilu Agbọ lati koju ẹsun pe o yinbọnpa ọkunrin agbẹ kan Julius Eku ni abule kanna ni ọjọ kẹrdọgbọn osu keji ọdun yi.

Awọn afẹsunkanni sọ pe ọdaran na pa ọkunrin agbẹ na l'ọna ti o lodi si ofin, eyi ti o mu ki awọn fa a wa sile ẹjọ.

Ṣugbọn bi awọn ti ka ẹsun na si ẹrun ọdaran ọkunrin yi tan ni Adajọ deejọ na Oloye J. U. E. Agbaza paṣẹ pe ki nwọn loọ ti i mọle, o si fi ọjọ bere iwadi lori ẹsun na si ọjọ karun oṣu kerin ọdun yi.

## Babasale Musulumi ku

Laipe yi ni agba oku Babasale fun ẹka Ẹgbẹ Musulumi Ila-Ọrangun Oloye Bẹlo Aromoge; eni ẹgọrin ọdun ni ki o tó fi aiye silẹ. Ọpọ ọmọ ati ọmọ-ọmọ l'o gbẹhin Ologbe na.

Ninu awọn Ọmọlẹoku na ni Ọgbẹni Karimu Aromoge, olokiki afọkuta ni Ila—Ọrangun, Iyaafin Ṣifawu Aromoge ti o jẹ Oludasile ile itura kan ni Ile Ife; Ọgbẹni Raimi Aromoge ti o jẹ ayafẹto ni Ikirun ati Ọgbẹni Alimi Aromoge ti iṣe Oniṣowo pataki kan ni Ibadan.



## Akeko ni ile Russia

Aworan ẹgbọ yi nṣe afihan ara ọpọlọpọ akẹkọ ọmọ ilẹ enia dudu ti o nkẹkọ ni ile Russia. Awọn wọnyi nkẹkọ ni ile ekọgiga Kiev University ni ẹka ibi igbaradi lati wọ ile ekọ na. Lati apa osi ni U Etuk, G. Danjuma, O. Adebisi lati ile Naijiria.




DANGEROUS DRIVING

# 1 8 42

IWE IGBAELODE DARA PUPỌ

1. Iwe gbogbo Agbo Ọmọde ati Agba 10k
2. Kurani esu marun Yoruba 55k Esu kan (25k)
3. Yasin ni Yoruba (10k)
4. Zabura ati itumọ (55k)
5. Zabura Yoruba (40k)
6. Iwe Aiye Akamara (40k)
   Iwe owe enia ṣoro 40k
7. Adedẹwẹ (35k)
8. Iwosan Ajẹbidan Ogun enia dudu (N3); Kekere (75k)
9. Iwe ala ni nla (N1. 50)
10. Kekere(30k)
11. Iwe oogun iwosan (N1. 5) Kekere (45k)
12. Itan Anabi ati Yisa (55k)
13. English Hausa Yoruba & Ibo Registered No 410 (25k)

FI OWO ATI STAMP (5k) RANṢẸ SI:

(1) Alufa Yisa Igbaelode N2/394a, Odoye Adeoyo Rd, P. O. Box 3365, Mapo Ibadan.

(2) Alufa Igbaelode, Moṣalaṣi Idi Işin St Isalẹ Koto P. O. Box 17 Ilọrin




# KERE O! KERE O!!

***Bi o ba je onisowo ti o nfe ki oja re maa ta; ti o si nfe ki oja re gbajumo kari aiye gegebi iwe irohin IMOLE OWURO ti gbajumo; darapo pelu awon enia afata ti o npolowo oja won sinu Imole Owuro.***

***Fun alaye ekunrere nipa bi o se nilati se e ati iye ti o nilati san; wa sile ise wa tabi ki o kowe si:***

**Advertisement Manager**
**(Imole Owuro)**
**N4/496B Yemetu Aladorin**
**P. M. B. 5230**
**Ibadan.**

# Olopa ba ise Jaguda jc l'Eko



QGAGUN OLUWOLE ROTIMI
Gomina Ologun Ipinle Iwo—Oorun

## Iree nfe Oba

AWQN enia ilu Iree ni iha Ila—Oorun Qșun ti rq Ijqba Ologun Iwq-Oorun lati tetq yan Qba titun si ilu Iree. Ebe na waiye ni Qja-Qba ni ilu na ni akoko ti nwqn șșetutu fun alaafia ati Idęra fun ilu wqn.

Ninu qrq rę Adele Qba, Oloye Emmanuel Araoye sq pe, awqn ti awqn ję Afębaję ti șișę t'awqn ni ibamu pęlu ifę Ijqba Iwq-Oorun pe ki awqn fi oruko qmqye ranșę lati oșu kęjq qdun ti o kqja.

Oloye Araoye sq pe lati nkan bi qjq kejilelogun oșu kęfa qdun 1972 ti Aree ana Qba Ezekiel Qlatunji ti waja ni itę Aree ti și silę ti ęnikęni ko si ti I gori itę na. O ni ilu ti ko ba ni Qba dabi mqto ti ko ni ijanu.

Nitorina, Adele Qba na rq Ijqba-Ologun lati tete ba wqn fi qwq si iwe Qmqye ti nwqn fi șqwq si wqn.

LOJIJI ni awqn Qlqpa Qtęlęmuyę yq si awqn alalupayida owo Naira, ti nwqn si ba wqn l'enu ise egbelę—gbida Kqressi Naira ti nwqn fi npa qmo araiye lękun.

Irohin lati ilu Eko fi ye wa pe, awqn alalupayida na kofura rara titi awqn Qlqpa Qtelemuye lati olu ile ișe wqn ni Eko fi yq si wqn nibiti nwqn ti nșișe ibi wqn na lqwq ninu ile kan ni Surulere bi nwqn ti nlu qkunrin kan ni jibiti egberun Naira lqwq.

Irohin na fi kun un pe, qwq awqn Qtele—muye na tę gende fakiafakia meji ti awon yio fi oro wa l'enuwo l'ori isele na.

Siwaju si I, irohin na so pe, o le ni ęgbaarun iwe funfun ti nwqn ge ni iwqn kqręęsi Naira pęlu awqn elo ișę jibiti ti awqn alalupayida na nlo ti qwq awqn Qlqpa Qtęlęmuyę na tę.

A gbq pe, ara jibiti ti awqn alalupayida na nlu awqn enia na ni pe, nwqn di awqn iwe funfun ti nwqn ge ni iwqn Naira-Naira ni idi kqqkan, nwqn si fi Naira kqqkan aladipq marun bo o niwaju ati lęhin lati maa fi tan awqn enia pe, awqn șe alupayida owo na fun wqn ni.

A gbq pęlu pe nipa iru qna yi, nwqn ti lu qpq enia ni jibiti nitoripe nșe ni nwqn maa nsq fun ęniti nwqn ba fęę fęșu se pe ki o mu aadqta Naira wa ki awqn fi șe alupayida qgqrun Naira fun un.

Nipa riri ti awqn qtęlęmuyę ri ibi ișę wqn yi, omoye kan fi ye wa pe odi ișę alalupayida ti wolulę paapaa ni ilu Eko.

# Owodunni jijo Egbe 45

EGBĘ kan ni Ogbemqșq ti a mq si "Owo dunni Young Association" ti fa qmq yq nibi ayęyę ijo ęgbę kan ti nwqn jo ni ayika Gbqngan ilu Ogbomqșq ni lqqlqq yi.

Gbajumq Onișowo mqtq (transporter) kan ni Ogbomqșq Qmq Qba G. N. Lawal Alebioșu ni Baba Egbę wqn, Qmq qba Mojoyin Laoye ti ișe Onișowo așq tita ni Ogbomqșq si ni Iya ęgbę wqn, Qgbęni Ganiyu Ajao si ni alaga ęgbę na.

Orișirișì awqn enia nlanla l'o wa nibi ijo ęgbę na.

Ara wqn ni Wahabi Saka Aolalubarika Qmqba Okun/qla Layęde, R. A. Sadiku, Amuda Ajao ati bęę—bęę lq.





Aworan oke nșe afihan Aręmqbinrin Qbabinrin ilę Gęęsi Qlqla Anne ati Baale rę Qgagun Mark Phillips bi nwqn ti nfi tęrintęyę da ogunlqgq enia ti o njuwo si wqn lohun bi nwqn ti ngunlę si papa qkq ofurufu ni ilę New Zealand lati woran Idije are idaraya ilę ti mba Gęęsi șepq, eyiti o waiye nibę laipę yi.

*Aworan ti ęgbę osi yi ni ti Qbabinrin ilę Gęęsi Alaiyeluwa Elizabeth keji pęlu Baale rę Qlqla Phillips bi awqn na ti ngunlę lati woran Idije ala na, Nibę ni oun ati qmq rę na kq pade lati esin ti qmq na ti lq sile qkq.

# IROHIN NI ONILUJILU

## Ada

Igbakeji Ọga ile iṣẹ Alafowosowopo agbegbe Oṣogbo Ọgbẹni Ifẹdayo Adejare ti re Ẹgbẹ Alafowosowopo ni ilẹ Naijiria lati nipa ninu eto faayegbonilẹ ti Ijọba Apapọ so l'ofin laipẹ yi.

Ọgbẹni Adejare pe ipe yi nigbati o nṣe ipade pẹlu awọn Ọmọ ẹgbẹ Alafọwọsowọpo Ireakari Ada ni ilu Ada ni iha Ila-oorun Ariwa Ọṣun Ọgbẹni Adejare fi kun un pe nipa lilowosi iru eto bẹẹ ni mekunnu yio fi gbadun ninu eto faayegbonilẹ na. O ni o tile yẹ ki o je iwuri fun omo Ẹgbe ti a ba pe won lati waa nipa ninu eto idagbasoke Naijiria

Lehin na, Alaga ẹgbe na, Alhaji O. M. Adewoyin so fun won pe ifowosowopo laarin Ẹgbe Alafowosowopo ile Naijiria ṣe pataki, eyiti o so pe yio mu ki iṣoro ti oga ile iṣe Ẹgbe kookan la maa dojuko dinku. O dupe lowo awon Ọga ile iṣe Ẹgbe na fun wiwa si ipade won

## Inisa

Gbogbo awọn Agbẹ Onikoko Ipinlẹ Iwọ—Oorun ni nwọn ti kesi lati darapọ mọ ẹgbẹ Alafọwọsowọpọ ki nwọn baa le tete r'ọna gbe e gba l'ori iṣẹ wọn.

Igba keji Ọga ile iṣẹ Alafọwọsowọpọ fun agbegbe Oṣogbo Ọgbẹni Ifẹdayọ Adejare ni o sọ eyi nigbati o mba awọn ẹgbẹ Agbẹ Odo Ọtin ṣọrọ laipẹ yi.

Ọgbẹni Adejare sọ pe o yẹ ki ifọwọsowọpọ wa laarin agbẹ Onikoko ati ẹgbẹ Alafọwọsowọpọ ti nra koko ki awọn agbẹ na le gbadun iṣẹ wọn. O kesi wọn lati tu aṣiri awọn Onifayawọ koko, ki nwọn ma si ṣe fi iwa jọ wọn.

Ni ipari, Ọgbẹni Adejare kesi wọn lati tete lo anfani eto atungbin koko, ki nwọn si tun koko wọn ti o ti ku gbin.

## Ikirun

NWỌN ti da ẹgbẹ ti njẹ Prestige of Nigeria silẹ ni ilu Ikirun laipẹ yi.

Baba ẹgbẹ na Ọgbẹni Wale Awojẹbẹ sọ fun wọn pe ifọwọsowọpọ larin awọn ẹgbẹ lati mu ki nwọn se aṣeyọri rere, ati ki ẹgbẹ nwọn si le jẹ awokọṣe fun ọpọ enia se pataki; o rọ wọn pẹlu lati maa pa ofin ẹgbẹ wọn mọ.

Akọwe ẹgbẹ Ọgbẹni Victor Ṣẹgun Agunbiade rọ awọn ẹgbẹ lati san owo iwọ—ẹgbẹ wọn ti o jẹ Naira mẹwa (N10) pẹlu Naira meji (N2) fun ipamọ oṣuoṣu.

Ọgbẹni Ṣẹgun Obembe, Wale Ọbasanmi ati Ọlasunkanmi, sọ pe awọn ki yio gba oṣelu l'aye lati ranwọ ẹgbẹ nabi o ti wu ki o ri.

Naira marundinlogorin ni nwọn kojọ ni ọjọ na.

# 7 11 52



Aworan ẹgbẹ yi nṣe afihan ara awọn agbayanu ọkọ oju omi ti ilẹ Gẹẹsi bi o ti ngbaruru l'ori alagbalugbu omi okun.

* Aworan ti oke yi nṣe afihan iru ọkọ oju omi kan ni ilẹ Russia, eyiti iṣe ti ẹgbẹ ọlọkọ oju omi kan ni ilẹ na.






Aworan ẹgbẹ yi nṣe afihan iṣẹ ọna pataki kan ti nwọn ṣe ni ilẹ Russia. Aworan na jẹ ti ere ti nwọn gbẹ ni iranti ara awọn olokiki ilẹ na ti o ti ṣe ohun ribiribi fun ilẹ wọn.

Awọn iru ere bẹẹ ni ẹ nwo ninu aworan ẹgbẹ yi.

26&27

# 32 38 48

# ỌMỌ FI ỌBẸ DUMBU IYA RẸ SINU ILE

IROHIN lati ilu Ibinni fi ye wa pe ọmọbinrin ọmọ ọdun mọkandinlogbọn kan ti fi ọbẹ gun iya rẹ pa patapata ni abuleko Ekaberu ti o jẹ ibuso mẹrinla si ilu Ibinni.

Afirohintonileti kan ti o sunmọ ile iṣẹ awọn Ọlọpa pẹkipẹki fi ye wa pe awọ kan l'o bẹsilẹ laarin ọmọbinrin na ati iya rẹ ni alẹ ọjọ 'ṣẹlẹ na titi oorun fi nkun oju olukuluku wọn ti awọn si lọọ sun.

Sugbọn nigbati o di ọganjọ oru ni ọmọbinrin na dide ni iyara tirẹ, ti o yọ kẹlẹkẹlẹ lọ si iyara iya rẹ, ẹniti o ti sunlọ fọnfọn ni akoko na.

Irohin na sọ pe l'oju oorun ni iya na wa bayi ti ọmọ rẹ na fi da ọbẹ de iya na l'orun ti o si dumbu rẹ lẹsẹkẹsẹ, nipa eyiti iya na fi di ero ọrun alakeji.

A gbọ pe laipẹ yi ni awọn da ọmọbinrin na pada wa si Naijira lati ilu Oyinbo nitori nwọn sọ pe " arun ọpọlọ" nṣe e.

Bayi, awọn ti gbe oku iya na lọ sile iwosan ilu Ibinni fun ayẹwo, awọn Ọlọpa si ti nfi ọrọ wa ọmọbinrin na l'ẹnu wo.

# 'Aburo Pa Egbon'

(Lati oju ewe kini)

ibiti Dokita na sun. Patrick Ubaka Obinwa ti iṣe aburo Dokita na yio si fi eedu kunju ki Dokita na ma baa da a mọ, oun ni yio si fi Dokita na han wa; Ohanuka ati Ibe (ti o ti na papa bora) ni yio si ma ṣọna."

Siwaju si i, ọdaran Ajuluchukwu sọ pe, "Ṣaaju ki iṣẹ pipa na too waiye, Udedibia sọ fun wa pe ẹgbẹrun Naira (N1,000) ni oun nikan yio mu ninu apapọ ẹgbeedogun Naira (N3,000) ti iṣe owo iṣẹ agbapa na niwọn bi o ṣe jẹ pe oun gan an ni oun nilati pa Dokita na, ki awọn onisẹ yoku si pin ẹgbaa Naira ti o ku. Ṣugbọn nwọn sọ pe emi Ajuluchukwu ko nil pin ninu owo na nitoripe Naira mẹjọ ojumọ owo yiya mọto mi lo kii yẹ l'ojumọ kan.

Bayi ni mo joko sidi kata ọkọ gẹgẹ bi iṣẹ ti nwọn fun mi ṣe, awọn yoku si lọ kuro l'ọdọ mi. Ko pẹ ni mo gburo ibọn, ko si pẹ lẹhin eyi ẹwẹ ni awọn janmaa pada de, nwọn ko sinu ọkọ, a si lọ kuro nibẹ.

BABA DỌKITA

Ṣugbọn ninu ọrọ rẹ nile ẹjọ na, Baba Dọkita na Alagba Obinwa sọ fun ile ẹjọ pe oun kanna ti oun bi Dọkita na ni oun bi eleyi ti o bẹ ọwẹ pa Dọkita na pẹlu. O ni agbako ni ọmọ na jẹ fun oun nitoripe o ti nfi igbakan d'ọdọ ẹmi oun baba rẹ paapaa kiri. O ni apania gidi ni iṣe. O ni ọmọ na ni o wa ni ipo ẹkẹrin ninu apapọ ọmọ mẹsan ti oun bi. Ẹjọ na nlọ lọwọ.

# POOLS! POOLS!! POOLS!!!

## Perm 7,9,11,24,27

Nap:- 5, 20, 26, 45,

Onje omo

2

3

13

14

28





PRINTED AND PUBLISHED BY THE PEOPLES STAR PRESS NIG. LTD. YEMETU ALADORIN P M B 5136 IBADAN OLOTU (EDITOR) LAWUYI OGUNNIRAN